Dajudaju ninu awọn eniyan ti o buru julọ ni ẹni ti ọjọ igbedide ba ba ti wọn si wa ni alààyè, ati ẹni ti o ba mu awọn saare ni mọsalasi

Lati ọdọ Abdullahi ọmọ Mas'ud- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Mo gbọ́ ti ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: "Dajudaju ninu awọn eniyan ti o buru julọ ni ẹni ti ọjọ igbedide ba ba ti wọn si wa ni alààyè, ati ẹni ti o ba mu awọn saare ni mọsalasi".
[O daa] [Ahmad ni o gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ nipa awọn ti wọn buru julọ ninu awọn eniyan, awọn ni ẹni ti ọjọ igbedide to le wọn lori ti wọn si wa ni alààyè, ati awọn ti wọn maa n mu awọn saare ni awọn mọsalasi, ti wọn maa n kirun nibẹ ati si wọn lara.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3375